# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

No 873 WEDNESDAY DECEMBER 16, 1964 [2D]

## Ẹniti Ebi Npa Ji Basikulu Gbe !

YABA:- Oju gba gbogbo enia ni fun ọdọmọdekurin kan, Tunde Mọmọh, ẹni ọdun mejidinlogun ti awọn ọlọpa mu wa siwaju adajọ Agba Ile ẹjọ giga, Yaba fun ẹsun ole jija ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi.

Ọga awọn Ọlọpa ti o ba ọdaran ọmọ na ṣẹjọ Ọgbẹni A Adeduro ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, ọdaran na ji Basikulu Rali kan' nomba J, T. 7917 gbe, o si gbe lọ si ọdọ Atunkẹkẹṣe kan ni nọmba 72a, Simpson Street ni Ebute Mẹtta pe on fẹ taa Atunkẹkẹṣẹ na fẹ ra basikulu na ni ọwọ rẹ sugbọn nigbati o bere iwe aṣe ti o fi ra basikulu na, ni ọdaran na ko si ri iwe aṣẹ mu jade ni o ba lọ fi oro na han awon Ọlọpa ni Tẹsan.

Nigbati adajo bi odaran na ohun ti o fẹ so ? Ọdaran na gba pe on jẹbi o si ṣe alaye pe ebi lo npa mi ti mo fi ji basikula gbe ati pe awon obi mi si ti ku. Ni adajo ba ni ki o lo fi ẹwon oṣu mẹfa jura.

# 'GBENRO BẸRẸ IPOLOWO IBO NI IPNLẸ IWỌ ORUN

**ẸFFỌN:- Ni deede agogo mẹjọ kutukutu owurọ ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ojo kẹdogun oṣu yi ni Alhaji D S Adegbenro Adele Aṣiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹra (A ) G. ba moto ayokẹlẹ rẹ ati awon ẹmẹwa rẹ kuro ni Ibadan lati bẹrẹ ipolowo apapo ibo osẹ kan ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria**

Irohin fi ye wa wipe fun odidi wakati meji ni mọto fi duro nigbati mọto awọn enia ti nha Alhaji Adegbeoro fi nkọja ni oju ọna ni Oke Ado titi de Mọkọla ni ana.

Bi awọn enia na ti nlo ni Ogunlọgọ awọn nsare jude ninu ile ti nwọn si nkesi Alhaji Adegbero ati awọn ẹmẹwa wa rẹ pẹlu adura wipe.

O dabọ o Alọ yio dara abọ yio sunwọn o ku asoju ṣẹhin Iwọ na yio ri eni ṣe bẹ fun o enyin yio bori ninu ibo ibo ti mbọ.

Ọlọrun yio pa alo ati abo nyin mo yio si ṣe asiwaju ati akehin nyin ninu irinajo nyin

Ni deede agogo mẹwa owurọ ni Awọn enia na de Ẹffọn.

Nigabati o ti ku ibusọ marun ki nwọn de Ẹffọn ni awọn ara ilu ti wa jo pade wọn loju ọna pẹlu ilu ati ijo orişirişi.

Agbọ wipe awọn ọmọ Ile iwe pẹlu to rẹpẹtẹ si oju ọna ni ẹgbẹ kini at ẹgbẹ keji loju ọna lati wọ inu ilu Ẹffọn ni owurọ ana

Nigbati gbogbo awọn enia na fi oju kan Alhaji Adegbenro Inu wọn dun, nwọn si nyọ ṣẹṣẹ.

Iki ibọn makanlelogun ni awọn ọdẹ yin nigbati Adegbenro wọlu

Gbogbo awọn agba ninu ilu na ni ko lọ si oko, ti nwọn si duro sile lati foju kan Adegbenro.

Ninu ọrọ rẹ, Alhaji Adegbenro ni on mọ ati daju wipe ko si ẹniti nṣe ẹgbẹ Dẹmọ ni ipinlẹ yi, şugbọn nipa ibẹru ati ijaya ni uwọn fi nṣe gbogbo ohun ti nwọn nṣe, nitoripe bi nwọn ko ba ṣebẹ wọn ko mọ ohun ti Ijọba Dẹmọ ipinlẹ na le ṣe si awọn ati ọba wọn.

Siwaju si i, Alhaji Adegbenro kesi gbogbo awọn enia na lati dibo fun ẹgbẹ Ilọsiwaju UPGA

O ni bi ẹgbẹ UPGA ba wọle, gbogbo rogbodiyan, aifọkanbalẹ, airi iṣẹ ṣe ati airoju ti o wa ni Ipinlẹ na nisisiyi ni yio kuro patapata

Ki Alhaji Adegbenro to pari ọrọ yi, nṣe ni gbogbo awọn enia na nkigbe "Awo! Awo !! Awo !!!

Alhaji Adegbenro ni on nlọ kakiri Ipinlẹ yi lati tọju awọn enia na silẹ fun ibo to mbọ eyiti gbogba wọn yio di ni ọgbọn ọjo oṣu yi

O ni ki awọn enia na o maşe jaiya, asiko ti de tan ti gbogbo wọn yio ni ẹkunrẹrẹ ayọ, ti nwọn o si lọ ninu ipọnju ẹgbẹ Dẹmọ oni Igba la nkan ilẹkun awọn enia na nisisiyi, bi Oluwa ba şi fẹ Igbala na yi o wọle ẹnikọkan wọn.

Alhaji Adegbenro ni ki iṣe awon enia ilu nikan ni on wa ri, awon ti nwon wa ni abuleko pẹlu, on wa lati ri won, on yio ma a lo sinu oko won lati lo wo won ninu irinajo yi.

O tun sọ siwaju si ninu ọrọ rẹwipe, ọrọ wa lẹnu awọn enia na şugbọn nwọnko le sọ ohunti o wa lọkan won jade o wa sọ bayi pe.

Mo mọ daju pe ọpọlọpọ enia ninu ti ẹ ti ni Baba ni ẹgbẹ Dẹmọ ti pa Baba, wọn, ninu ija igboro ti ilu ẹlomiran pa bamu bamu, wọn si ẹwọn laiko fọle, bẹni"

Ẹpọlọpọ ni nwọn ti fi ẹsun eke sun lẹsẹ tabi ti nwọn ti sọ di alabuku enia, ti elomiran ko jẹ alaiye tabi ero ọran, nipa fifi ipa mu enia pe ki nwọn o ma a fi ipa kigbe PAWA¡

"Awọn ti nwọn ti mu ọti ogogoro yo, tabi ewe taba 'igbo, ni nwọn si sa ina bọ ile ati mọto awọn enia',

Alhaji Adegbenro wa bere pe "E wo ni to ijaiya fun nyin ninu eyiti a ka silẹ wọnyi Lati eyiti ẹgbẹ Afẹnifẹ tinş igbati pinlẹ y , mẹ re abi e Ijọba ni ẹgbọ wiọto tọnile melo sunu? pe na da ina

*WO OJU EWE KEFA*



**Alhaji D. S. Adegbenro.**

## IPADE UPGA

Awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA yio se ipade lo i ni dee de agogo marun irọlẹ ni opopo Luther ati Gbamgbose

Awọn ti o wa ni Ebute- Metta yio ṣe ipade ti wọn ni Gbangba arin ọja Oyingbo ni agogo marun kanna

Nwọn npe gbogbo ọmọ ẹgbẹ lọkunrin ati l'obinrin.

Tete ra Irohin Imọlẹ tirẹ lọla ki o ba le mọ ibi ti wọn ma ti sẹ ipade.

# Ohun Ti O Ni Ẹtọ Fun Awọn Ẹgbẹ Oṣelu Lori Idibo Yi

**Lati Ọwọ Bayọ Tiamiyu**

Ẹnyin Olugbe ilẹ Naijiria ati paapa julọ fun awọn gbẹ Oṣelu ilẹ Naijiria ọrọ diẹ ti mo fẹ fi to nyin lati lori idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ ijọba ilẹ Naijiria ti a ṣe idibo rẹ ni ọgbọnjọ oṣu yi lori bi eto idibo a yio ṣe lọ laisi pe ija tabi ọna eru bayi ni pe ki olukuluku to ba mọ pe ọmọ ilẹ Naijiria ni on iṣe ati pe ti Oluwa rẹ ba nfẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria bayi ni ọna gẹgẹbi idibo na yio ṣe lọ ni ọna ẹtọ laisi ija tabi ọna ifi iya jẹ awọn enia kan.

Mo ro pe larin ọsẹ to kọja ni Alakoso ilẹ Naijiria Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe si fi to gbogbo awọn olori ẹgbẹ Oṣelu ilẹ-wa leti lati lọ ni ọkan suru ati bi iṣọkan yio ṣe wa larin awa enia ilẹ Naijiria



Alhaji Ahmadu Bello
Olori Ẹgbẹ N P C

Mo si kan saara si gbogbo ọrọ ti Alakoso wa na sọ eyi to jẹ pe o yẹ ki olukuluku to ba ni iwa Ibajẹ tabi awọn enia ti ko mọ Ọlọrun ni lati lọ ronu nipa rẹ lati fi ṣe iwa hu.

Gẹgẹbi awọn olori ẹgbẹ Oṣelu wa to fi nsọ ninu eto ipolowo ibo wọn pe idibo to mbọ yi yio jẹ itan ninu awọn ibo ti nwọn nṣe ni ilẹ Naijiria, emi si gba ọrọ na gbọ ati pe emi ko lodi si ọrọ wọn rara.

Ṣugbọn ohun ti gbogbo wa ti mọ daju pe ti enia meji ba nja ẹnikan ni yio ni agbara ju ninu awọn meji na. Nkan ti a ti mọ pe ninu awọn ẹgbẹ Oṣelu to wa ni ilẹ Naijiria bayi eyi to jẹ pe nwọn ti pin ara wọn si ọna meji eyi ti UPGA ati NNA nkan ti a ti mọ daju ni pe ẹgbẹ kan ni yio bori ibo na ninu awọn ẹgbẹ na.

Gẹgẹbi ọrọ ti mo ni Alakoso ilẹ Naijiria Dokita Nnamdi Azikiwe sọ ti mo sọ pe emi ko le mu ẹnu kuro nipa rẹ ni pe eleyi jẹ ikilọ gidigidi fun awọn ẹgbẹ Oṣelu wa lati lo mu iwa rere ti o ba si ninu wọn ti iwa ika wa ninu rẹ lọ ronu jinlẹ ki nwọn tele ọrọ ti Alakoso wa sọ fun wa.

Eleyi si ti fi han gbangba pe gbogbo ọrọ ti Alakoso wa nsọ pe otitọ ni nitori pe ti a ba gbe oye wo nkan to nṣẹlẹ ni awọn ipinlẹ Naijiria a o si pe ko ba oju mu rara nitori pe ti a ba nṣọkun a ma riran to ba jẹ owe ni ki o jẹ ti Olotu ati awọn alagba wa.

Ọpọlọpọ awọn enia ti ko mọwọ ti ko mẹsẹ ni ilẹ Naijiria loni lo di ero ẹwọn ti ẹlomiran ti padanu ẹmi rẹ lori igboke -gbodo eto ọrọ Oṣelu to wa ni ilẹ Naijiria bayi.

Eleyi yio jẹ itiju fun awa ọmọ ilẹ Naijiria ni ilu okere eyi to jẹ pe iru iwa aibikita bayi ma nṣẹle ni ilẹ Naijiria. Mo ro pe gbogbo awọn ilu miran ni yio ma kan sara si ilẹ Naijiria lori akitiyan ti a ṣe lasiko ti ija



Dokita M I. Okpara
Olori Ẹgbẹ Alakoso

nla kan to ṣẹlẹ ni ilẹ Congo eyi to jẹ pe ilẹ na ko ti ni eto Ijọba rere titi di oni yi.

Ṣugbọn ti awọn Olori ẹgbẹ oṣelu ilẹ wa ko ba lọ san ṣokoto wọn ki o le gbọin gbbin bayi ki Oluwa Ọba Olodumare mi jẹ ki iru nkan bẹ ṣẹlẹ ni ilẹ wa ọrọ idibo to mbọ yi ko le mu iwa ika lọwọ ati pe ti awọn ẹgbẹ oṣelu to wa ni ilẹ Naijiria ba da ara wọn loju mo rọ pe ko si nkan to le fa ti a le ma fi iya ma jẹ awọn enia ti ko ba ti ṣe ti ẹgbẹ ti oṣelu kan tabi pe ki a ma lo agbara ki a ma gbe wọn s'ẹwọn ia jale tabi pe awọn pa enia

Eleyi yio i han pe iru awọn ẹgbẹ oṣelu to ba iru iwa bayi ko ni e ia lẹhin tabi pe awọn enia ilẹ Naijiria ko fẹ iru ẹgbẹ bẹ awọn alagba lo ma npa lowe pe Ip ko taja ipa ko tun raja nitori eyi yio dara pupọ bi awọn Olori ẹgbẹ oṣelu to nhu iru iayi tete jawọ kuro ninu iwa ti ko dara eyi to jẹ pe iriju ati aimọ Ọlọrun lo mu lọwọ.

Ohun to jẹ pe o le mu r gbodiyan wa fun awa Olugbe ilẹ Naijiria to fẹ mu iru bẹ lowo ati olukuluku awọn ẹgbẹ oṣelu pada Wo oju ewe Karun

## EJONGBORO K'ABỌ

Lati Ọwọ Ẹrukobodo Eko

Inu mi dun, ara mi si ya gaga nigbati mo gbọ irohin wipe, Amuludun, Ọkunrin kọrọbọtọ bi ọka; Ọkọ-ọmọge ti mọ adape Orukọ rẹ ni "EJONGORO" ninu iwe Irohin Imọlẹ, t o ti dakan ṣe abẹwo rẹ lọ si Ilu "Arikọgbọn" lati nkan bi oṣu mẹfa sẹhin ti pada pe,



Alagba Ẹrukobodo

Ayo mi si ipada bo "EJONGBORO" ti wipe gbogbo ohun ti ati nreti lati gbọ fun idagba sok e ilẹ wa ati gbogbo ohun ti o ti nru wa loju ati gbogbo ohun ti a ii ngbọ ti a mọ tumọ re ni 'EJONGBORO" yio fi han wa kedere uinu Irohin-Imọlẹ.

Mo fi eyi kẹwọ ihin si Ajẹgboro dagba ti o ti nṣẹlẹ de Ejongboro wipe o ku afijuba o ku iranlọwọ nla ti o ti nṣe lẹhin Ejongboro.

Mo tun ki ẹnyin onkawe ẹlẹgoẹ mi wipe ẹ ku afojuba;

Ohun pataki ti mo sẹ sọ fun ẹnyin nkawe Ironin Imọlẹ ni wipe enikan ki lọ si Ilu Arikọgbọn ki o maṣe mu Ọgbọn ati ohun rere bọ nitori ni o d'ọwọ nyin ẹ maṣe jẹki nwọn fi Irohin ti Ejongboro mu bọ pitan fun yin

E tete ṣe eto bi e o ti ṣe ma si Irohin Imọlẹ nyin gba fun Irohin aladun ti Ejongboro mu bọ.

A ke si Ejongboro wipe ki o tete fi Irohin tuntun ti o mu bọ lati Ila Arikọgbọn sode ati wipe idiwo nla ni o jẹ fun wa bi EJONGBORO ba le ṣe eto ohun tioto toye we lati re bi egbe UPGA ba bori idibo Ijọba apapọ ti ojo rẹ kusi dede y. ao ma reti o Olotu eku afojuba oko er tun ku Imura sile fun ọpọldibo rẹpẹtẹ tia i reti ojo na lowọ-lowọ yi

Ajinde ara yio maa je fun nyin ati fun gbogbo awa omo egbe UPGA jake jado ni igun mererin Ile Naijiria Ako ni see ti lagbara Baba loke

# IWE SI OLOTU

## Ireti Kia Fun Ẹgbẹ UPGA

Olotu: Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi ni aiye diẹ ninu iwe nyin Oloyinmọmọ lati fi ye Dokita Michael Okpara' Alhaji Dauda soroye Adegbenro Mallan Ami nu Kano ati Ọgbẹni Joseph Tarka pe ki nwọn ma ṣe bẹrẹ rara ati pe ireti si wa fun ẹgbẹ ilọsiwaju Naijiria yi ti iṣẹ ẹgbẹ UPGA.

Otitọ ni awa ko si ni ilẹ Naijiria ṣugbọn irohin to nde ọwọ wa ti fi han wa pe ẹgbẹ na ni yio bori idibo to mbọ yi eleyi ti tun da wa lo ju pe ẹgbẹ Olomi NPC Dẹmọ NNDP MDF ati ẹgbẹ NDC ti nwọn jijọ paga wọn pọ yio si kuna patapata ninu idibo to mbọ yi Otitọ ni a ngbọ pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ wa ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria pe gbogbo wọn lo wa lọgba ẹwọn bayi ṣugbọn awa ni ireti pe ti ẹgbẹ U P G A ba ti mọle gbogbo nkan ni yio rọgbọ fun awọn olugbe ilẹ Naijiria patapata.

Olotu m o dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi ajindẹ vio si ma jẹ ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ amin

Emi ni
Ọladele - Fakoya
Ijẹbu-Ipẹru.

## Ọlọpa Ẹ Gba Wa O.

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu Iwe nyin Oloyimọmọ lati kesi Ọga agba awọn Ọlọpa to wa ni gbegbe Ikẹja lat ba awa enia ilu Mushin ati s h o m o l u ṣe amojuto awọn nkan to nṣẹṣẹ si wa niawọn ilu meji yi eyi to jẹ pe ko si ifi ọkan balẹ lati nkan bi oṣu meji sẹhin to jẹ pe ojojumọ ni awọn Ọlọṣa si ma nyọ wa lẹnu ati pe a ko le sun ni oru to fi jẹ pe awọn Ọlọpa ra ko ni jẹ ki a gba dun rara.

Inu wa yio dun bi ọga Ọlọpa ti agbegbe Ikẹja ba le gba wa lọwọ awọn Ọlọṣa na lati le fun awọn ilu meji yi ni Ọlọpa lati ma ṣe amojuto ilu na to bẹ di oru. Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ Amin

Emi ni
Mushin Bisi Onatade.

## Ẹlẹya Ẹgbẹ Dẹmọ Ku Si Dẹdẹ

Olotu, jọwọ gba mi ni aye rai rẹ diẹ ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati fi ye awọn ọmọ ilẹ Yoruba to jẹ pe awọn ti orjẹ ni nwọn nba r in lati tete pada lẹhin ẹgbẹ Dẹmọnu eyi to jẹ pe ko si ire kan to le ṣe fun wọn lẹhin ọla bi ko ṣe pe ọra gẹgẹ bi nwọn yio ṣe ta nyin fun ẹgbẹ Olomi NPC ti ẹgbẹ Olomi na yio tun ta nyin fun ilẹ Arab

Ṣugbọn idan loju si ti wa pe ẹgbẹ Dẹmọ ti ku patapata ati pe ẹjọ ẹlẹya wọn si ku si dẹdẹ lagbara Oduduwa Ẹnyin ọmọ ile Yoruba ti ẹ ba gbọ gbi! ki ẹ mọ pe Dẹmọ lo jabọ lọjọ ti a ba ngbọ abayọri eto Idibo eleyi si ti han gbangba pe ẹgbẹ na ti ku ṣugbọn mo fẹ fi to ẹnyin enia wa to jẹ pe ẹgbẹ na n ẹ nro pe o le tọ nyin s na bi ko ṣe pe ọna okunku biribiri ni yio tọ nyin si

Nitori na o di ọwọ nyin ẹnyin ọmọ Oduduwa mo si rọ nyin ki ẹ dibo nyin fun fun ẹgbẹ ilọsiwaju eyi ti iṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ ni ilẹ Yoruba ọrọ;die ni a nso fun ọmọ luabi to ba d inu rẹ yio di odindi.

Emi ni
OKEYA Olu. Ọlalere

## Owo T i Awolọwọ Na Si Ariwa Ni a Fẹ Gba Pada

Olotu Inu m i yio dun ti ẹ ba le fun mi ni aye diẹ lati fi ye awọn olori ẹgbẹ Afẹnifẹre p e a w a ọmọ Ogbomọshọ. Ẹdẹ ati Ejigbo ko ṣe ẹgbẹ Dẹmọ bi ko se pe owo ti olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Oba f ẹ m i Awolọwọ ti na si Ipinlẹ Ariwa i l ẹ Naijiria ninu ọdun 1959 lasiko idibo ni awa enia na fẹ gba pada lọwọ ẹgbẹ D ẹ m ọ nitori pe a si ti mọ pe ko si ibi kan t i awọn ẹgbẹ n ti nri ọwọ bi ko ṣe lati ọdọ ẹgbẹ Olomi ẹkọ NPC

Nitori a fẹ ki awọn olori wa lọ fi ọ'an balẹ p e a ko ẹgbẹ wọn bi ko ṣe pe lati gba owo ti ẹgbẹ Afẹnifẹre na si Ipinlẹ Ariwa pada

Awa si ni igbẹkẹle ninu Oloye Awolọwọ ati Adele rẹ Alhaji D. S. Adegbenro

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio si ma jẹ o, ọkọ ọba k o ni sa nyin lẹsẹ (Amin).

Emi ni,
Adebọla


EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

**TESSYDRE**

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti meji irufẹ rẹ kosi kakiri, igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu EHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala lọsan tabi sun awọn iya wọn gbogbo Ogorun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo si ẹnu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ ṣugbọn kosi eyi ti le fi we egbogi Tessyd re rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu Agonyin (GHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni wọn si nlo fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wewa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ri inu iwọ aiperi osiinu fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ ṣiṣu, gburu tabi ikolokun nnu ara sisu, Inu kunkun iro aftẹfẹ ati orisirisi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu ni ba Ehin HIHU" gbogbo. Tessy dre a ma mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati Isan ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba ṣe ami rara niwọn igba ti wọn ba ti nbọsẹ dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbaya wọn i wọn jẹun dara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

Bere Egbogi Ni Ṣọbu Awọn:

WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba



**Ipolowo Oja Rẹ 'Ko Ti Yege**

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO OJA RẸ
SINU
**IROHIN IMOLẸ**
T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE IPOLOWO OJA RẸ SI
ADVERTISMENT MANAGER
**IROHIN IMOLE**
16, Bamgboṣe Street Phone 21955

# Awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko Ṣe Apejẹ Alarinririn

## Lati Ọwọ Alhadji Y. A. Disu

EKO-: Irohin ko to afojuba ni apejo ti awọn Ọga Agba Ibiṣẹ igbimọ Ijọba ibilẹ Eko (The Association of Lagos City Council Senior Staff) ṣe ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Gbọngan "King George V Memorial Park" Onikan lati ba awọn Ọgbẹni L. J. Mayaki L L O. B L. O. O. N. Adeniyi Coker



Alhaji Y. A. Disu

M F R Duro Deede, O. Ogundiya B. Sc. D M I C E, A. Odukọya A A C C A, A I M T A ati Hadji H A B Fashiro L L B.. B. L. yọ ayọ fun Ọla ti Gomina Agba apapọ Ijọba Naijiria fi da wọn lenulọlọyi Oloye T. A. Doherty ti i wọn si yan si aye alaga lọjọ na. Ọgbẹni Akin Mumuney si sọ ọrọ apọnle pupọ nipa alaga na, ioti ṣe jẹ gbajumọ ati oselu ... ati bi ... si ... ṣe j... onimlọ to Oloye na si pi... n iwuri nipa ibiṣe i bimọ Ijọba ibilẹ Eko bi ibiṣẹ ... ṣe bẹrẹ a t i ... si ṣe ngberu siwaju ... si v... ti titi o fi di ... oloni Ọgbẹni Ade Pe... si se apọnle pupọ nipa awọn Ọgbẹni L. J. Mayaki, Adeniyi Coker(Duro Deede S. O Ogundiya, E A. Odukọya ati Alhadji H. A. B. Fasiro bi nwọn ti ṣe nfi gbogbo ara nṣiṣẹ igbimọ Ijọba Ibilẹ E o si, ti nwọn si ngbe Igbimọ na ga pupọ ni gbogbo – igba O ni Olukuluku wọn ni o nṣe iṣẹ ododo papa pa ọgbẹni Mayaki ati Ọgbeni Adeniyi Coker. Ọgbẹni O. A. Ladẹhinde si d u p ẹ fun awọn ti nwọn wa si ibi apejẹ na ọmọ Ọba Oloye Amiau Kosoko ti a p e l e orukọ rẹ nję "Gbajumọ-Afinju Oloye" si gba adura fun awọn olori rẹ na ti Gomina Agba da lọla.

Ajeti orişirişi adidun ati orişirişi ọti ni n w ọ n pese fun ogunlọgọ awọn eniyan jankanjankan. p a p a fun awọn O l o y e Onifila funfun ti nwọn wa si ibi aşeye na. Awọn alulu bẹ mbẹ ati awọn onifere si şe wabiwọsi ere ijo ọjọ na si buaya, o le gongo, irohin o si to afojuba ni o si jẹ. Ọpọlọpọ awọn oşişẹ igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko ni awọn Ọlọla ti o wa si ibi aşeye na ni nwọn si nla yo mọra bi kokoro l'alẹ ọjọ na. Ọla yio ma a ba ọla ni ile o ki Ọlọrun si fun awon ti nwon da ni Ọla ni ẹmi gigun ti o ni ore ninu o.

### LATI OJU EWE KEJI

şi ipinlẹ rẹ ti o ba wa mu pe ki asepọ wa fun awa Olugbe ilẹ Naijiria nitori eyi ẹ jẹ ki a lọ mu wa bayi kuro larin wa ki a si jẹ ki eto ibo to mbọ yi lọ ni ọna ẹtọ laisi pe awọn ẹgbẹ Oşelu kan to nse akoso Ijọba kan nfi agbara mu awọn ẹgbẹ Oşelu to ba jẹ Alatako si wọn o di gba diẹ na.

---

# IDIJE ! IDIJE.

A fi eyi kede fun awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ati awọn Ọmọ karọ-o-jire pe a nfẹ

## ITAN L'EDE YORUBA

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori ẹrọ Redio ri Ẹnikẹni ti o ba si bori yio gba

## (£5) PỌNUN MARUN

Akiyesi;- Kọ itan tirẹ ki o ha ... r kete, ti ẹniti ko ba han a o fa ya ... i, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipa ninu Idije na. ITAN ẹniti o ba si daraju ni a o tẹ jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ yi a o si fi lọ(£5 Postal Order) ranşe si

Fi Stamp Tọrọ (3d) ranşẹ fun ghigbe Pọnun marun (£5) ti o ba jẹ pada si ọ. K o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranşẹ pelu Stamp tọrọ rẹ si wa. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranşẹ siwa ti o ba jẹ owo na a ko ni fi ranşẹ si.

Orukọ.........................................

Ibugbe.........................................

...................................................

Fi itan rẹ ranşẹ si:-

**Olotu Irohin Imọlẹ**
16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.

---


# Gbanjo ! Gbanjo ! !

F N ỌDUN KERESIMESI

A ni lati fi kede fun awọn onibara wa pe Ọja gbanjo wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/11/64. Tete ra tir ki o to kase nilẹ

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Bọọsi Mushin, sọkale ni Atẹ ọlara Bus Stop Bere ladipo Street ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRE. Ti o ba de ibẹ tan, wa be re Nomba 5, Alaba Stree Mushin, ile işẹ wa dojukọti ODUS SURF"

AWỌN ỌJA WA

Olubori Egbogi Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin tite ati ẹru şişe 20s di 17 Iwe Afọşẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3/6 di 2s 6d Turari Isegun Aje 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo niti oke yi Turari ti o wa ninu pakẹti jẹ 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lẹsin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book di 1s 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Forms Certificate of Apprenticeship (meta) 17/6 di 10/6d

ỌJA TITUN TI A ŞEŞE RI GBA

Abrle mimọ fun adura tete Idalẹju (orişirişi awọ pu Turari.

bẹla mimọ fun itaja (Kowo wole pẹlu Turari 20/-
„ „ „ Işegun ẹ pẹlu Turari 20/-

Lofinda tabi Ororo ipara fun itaja, Işegun Ajẹ ati arisiki 30/- Igo kan

Fi owo ranşẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—

J. O. Shoyinka
Alaba Street
5. MUSHIN.

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

NO 873 WEDNESDAY DECEMBER 16, 1964 (2D)


## Awon Ọlọja Binu Kọ Ọja Silẹ

KANO; Ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kẹtala oşu yi' ni gbogbo awọn enia ilu Kano lọ si ọja ti nwọn ko si ri ẹiyẹ ninu ọja bẹni awọn iyawo ile gbogbo ko ri nkan obẹ ra nitoripe awọn onişowo gbogbo ti nwọn nta ọja na ni nwọn ko ko ọja wọn si ode.

Onirohin wa lati ilu K a n o ti ye wa wipe eyi lo di ọjọ keji ti awọn ọlọja na ko lọ si ọja lati lọ ta ọja wọn.

O tun fi ye wa wipe, awọn ọlọpa mu awọn o n i ş o w o ọja na meje. Ohun ti awọn ọlọpa na sọ fun oniwe irohin wa ni wipe, awọn ti fun wọn ni i w e pe ki nwọno maşe ta ọ j a ninu isọ wọn şugbọn awọn enia na ko gbọ aşẹ ti ti ọlọpa pa fun Awọn ọlọja yoku ti lọ fi oju kan Alhaji Bayero ti ọba ilu Kano nipa ọrọ na, A si lero pe ọba yio pari ọrọ na larin wọn, şugbọn awọn ọlọja na ko ti ma a ta ọja wọn ninu ọ j a na titi di bi ati şe nkọwe yi.

B nwọn ba ti pari ọrọ na si, ẹ o ma gbọ o.

# AWỌN ỌMỌ ILU ILESHA KO HA NI DIBO BI ?

**ILESHA:— Gbogbo ile lo kunşọsọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ ọkẹ aimoye awọn ọmọ Ilesha nile ati ni oko ti nwọn wa ninu ipade pajawiri kan ti awọn enia na are şe ni alẹ ana ọjọ Isẹgun ti işe ọjọ kẹdogun oşu yi.**

Gẹgẹbi irohin ti oniwe Irohin wa ni Ilesha fi ranşẹ si wa lẹhinti nwọn pari ipade wọn tan ni alẹ ana.

A gbọ wipe awọn enia na ti pinnu, nwọn si ti gba wipe awọn koni dibo ni ọgbọnjọ oşu yi ti gbogbo enia yio dibo bi Ọgbẹni Yinka Shiyanbọla ti awon ọmọ I l e s h a fẹ dibo fun ko ba ni ẹtọ pe ki awọn dibo fun un mọ.

Agbọrọsọ awọn ọmọ Ilesha şe alaye fun oniwe Irohin wa wipe gbogbo awọn ni awọn ti yan Ọgbẹni Yinka Shiyanbọla ni Asoju awọn lati dibo fun lọ si ile Igbimọ Asofu Apapọ Ijọba Naijiria ninu ibo ti mbọ yi.

Şugbọn lẹhin ti awọn ti mu ẹnitio mu awọn tan, ni Oloye Olu Akinfosilẹ. ti ise Alaga Igbimọ Amuşẹşe ẹgbẹ Alakukọ tun lọ gbo ẹlomiran ni imọran pe ki a fi orukọ rẹ ranşẹ si ẹgbẹ gẹgẹbi Asoju awọn ni agbegbe na,

Irohin sọ pe, o ti le ni oşu meji ti awọn enia na ti mu ẹniti o wu won, e'eyi ni Ọgbẹni Yinka Shiyanbọla.

OTITỌ ỌRỌ

Lẹhin oşu meji ti awọn si ti fi orukọ Shiyanbọla ranşẹ, pari ohun ti awọn yio ni ẹlomiran na tun fi oru ọ rẹ ranşẹ, gẹgẹbi imọran ti Oloye Akinfọsilẹ fun un.

Lẹhin ọjọ mẹta si asiko yi, ni Ọgbẹni Shiyanbọla ri iwe pẹlẹbẹ kan lati ọdọ awọn agba ati aşiwaju ẹgbẹ gba, wipe ki o wa ki awọn



Oloye Akinfosilẹ
Alaga Igbimọ Amuşẹşe
Ẹgbẹ Alakukọ

pari ija to wa larin wọn (ija ti ko si)

Ninu ipade na Oloye Akinfosilẹ ati Ọgbẹni E S McEwen wa ninu ijọko ọjọ na, lati wa pari "Ija ati ede aiyede" eyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ pe ko si ija larin awọn.

HUNNUHUNN

Awọn ọmọ ẹgbẹ na n awọn ti gbọ hunnuhunnun labẹl. wipe ẹniti Oloye Olu. Akinfosilẹ fẹ yan ni awọn Asiwaju ati agbalagba ẹgbẹ na fẹ gbe sode nisis yi, ki nwọn si kọ ọgbẹni Shiyanbọla ti gbogbo awọn nfẹ silẹ.

Awọn ọmọ Ilesha wa şe ilọ bayi pe," ohun ti o ba şe ti ẹ ko ba fi m u ẹniti a fẹ eyiti i ş e Shiyanbọla awọn ọmọ Ilesha y i o ka ọ r ọ na si rik si nitori pe, Oloye Akinfosilẹ t i ni irira ati keeta si ọgbẹni Shiyanbọla l ti ọ j ọ pipẹ sẹhin wa.

Siwaju si i, awọn enia na ni,"Ohun isoro ti Oloye Akinfosilẹ fẹ da ọwọ le yi yio di ariwo nla ti gbogbo aiye yio gbọ igbe a w ọ n ohunti yio wa buru j u l ọ ninu ọtọ na ni wipe, ayorisi rẹ le fọ ẹgbẹ Alakukọ si wẹwẹ ni agbegbe na

A si ti şe tan fun ohun yowu ti o le de Bakanna ẹwẹ ni a si ti tun şe ipinnu wipe bi ẹ ko ba yan Ọgbẹni Shiyanbọla ti gb o g b o wa nfẹ, a ko nidibo ni ọjọ ibo ti mbọ yi fun ẹniti ko tẹ wa lọrun ti ẹnikan fi tipatipa yan wa"

Nipari ọrọ awọn enia na nwọn kesi gbogbo awọn agbagba ati Asiwaju ẹgbẹ Alakakọ ti nwọn wa ni iha Gusu Ilesha pe Ẹ ba wa kilọ fun Oloye Akinfosilẹ, ki o maşe ba irẹpọ ajọşepọ ti o wa larin awọn lati ọjọ pipẹ jẹ.

Ni ipari ọrọ wọn, nwọn kesi Oloye Akinfosilẹ pe ki o ma da edeaiyede silẹ larin awọn.

## Adegbenro Bẹrẹ Ipolowo Ibo ni Ipinlẹ Iwọ Orun

Lati Oju Ewe Kini

Alhaji Adegbenro ati awọn ẹmẹwa rẹ yio lọ si aiyede, Oye, Ire Egosi Itapa osi Ihele Ilesha Ilaro Aiyegunlẹ Ilagbo Iddo osi Otun Owokoro. Ale Afao Igbesa Iluomoba, Aisegba, Agbado Ode ati Ado-Ekiti ki nwọn o to tun pada si Ibadan.

Onirohin wa kan ati ayan fọto kan ni o ba Alhaji Adegbenro lo si irinajo na bi nwọn ba si ti nlọ ati ọrọ aworan awọn enia ti o ba nsọ pẹlu aworan awọn enia ti nwọn nlọ gbọ ọrọ rẹ ni ẹ o ma a ri ninu iwe Irohin wa lojojumọ.

Awa oniwe Irohin Imọlẹ na ki Adegbenro pe o dabọ o.


## ADURA JẸ J'OGUN LỌ

| | |
|---|---|
| Iwe Adura pataki fun Arisiki lati ilẹ Mesira | 2/6 |
| Iwe Adura Akanşe ati apẹrẹ ile aiye | 2/ |
| Afọmọ – isin Ojişẹnla Muhammed | 1/ |
| Iwe Itumọ al ati Adura Ala Ibanujẹ | 3/6 |
| Iwe Aniyan Irun ojojumọ ati Aniyan pataki fun Musulumi | 1/ |

Tete fi Owo ranşẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Naijiria
(Leti Ọja Jankara l'Eko)



Printed And Published by Modupe Printing Press, 16, Bamgbọşe Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos (16/12/64)